# OWE ILẸ YORUBA

## Ti ALUFA B. A. WINFUNKẸ KỌ SILẸ

Nko kọ iwe yi lati fi yin Ẹni-ọwọ B. A. Winfunkẹ ẹniti gbogbo enia mọ, ti a si pe ni "Winfunke Olowe" nipa lakaye ati ọrọ rẹ ti o kun fun ọgbọn bẹni iwe yi ki ṣe lati fi ba a p'olowo oja rẹ. Iwe Owe yi papa ni yio p'olowo ara rẹ.

Ṣugbọn ẹnikẹni ti o wun ko ṣe ti o ba n ifẹ ilu tabi ti ori-lẹede rẹ ni ọkan, y o gbidanwo lati fi awọn ohun to niye lori s lẹ fun awọn iran ero-ẹhin, ki atọwọba iṣẹ awọn baba nla wa ma ba di ohun igbagbe.

Bi o ba ṣẹ pe ni Ilu Gẹsi ni a ri enia ti o nronu ati fi ohun ọgbọn ati awọn iwe Owe ti o pe ṣ i Ẹni-ọwọ Winfunkẹ yi silẹ n, Ọba Ilu Gẹsi iba ti da a l'ọla tipẹ-tipẹ, ṣugbọn ni ilu awa Enia Dudu, "Ol wọ n kan ni aye mọ" Ẹmi ifi arada ikan ti Ẹ ọwọ W nfunkẹ ni l ti kọ awọn Owe wọnyi ati lati ṣe eto wọn ni ilu ọna bayi jẹ ohun ti o yẹ ki o kun ọmọ Yoruba l'oju.

Ọlọrun ko da wa dogba; O fun olukuluku ni ẹbun tirẹ lọtọtọ. Ebun ti Ẹnrowọ Winfunkẹ yi le ma kun wa loju l'oni ṣugbọn l ọ a, a mọ wa sure fun u ni iṣẹ ajẹ-lọ-titi yi.

Fun ọdun pupọ ni mo ti k yesi ami ati ẹbun ti Olodumare fi da Ẹn-owọ Alufa wa yi l'ọla mo si ri abangba pe. "Ika Olorun" (finger of God) wa ni ahọn rẹ, ohun rẹ, ati opọlọ ori rẹ: lati lo wọn fun agbedide orilẹ ede wa, l'ọna yi fun iran to mbọ lẹhin ola.

Bi a ba ri ẹ ikan ni Iwe Owe Ilẹ Yoruba ti a kojọ yi ba ṣe l'ore, njẹ Iṣẹ Ẹ ọwọ B A. Winfunkẹ ko lọ lasan. Lotọ ọpọlọpọ ọ t awọn le rufẹ ako'ọ pe-tẹ Iwe Owe Ilẹ Yoruba, ṣugbọn bi a ba fi ara balẹ ka awọn Owe Alufa Winfunkẹ yi, ao ri pe akọ ede Yoruba ni tirẹ jẹ; nitorina o yẹ ki awọn ewe iwoyi mura lati gun ategun owe ti Ẹni-ọwọ Winfunkẹ fi lelẹ yi, ki a si gbiyanju lati sa ipa lati ṣe ju t rẹ lọ fun ire ilẹ wa.. Owe di owe Ẹni-ọwọ wa (B. A. Winfunkẹ) ti o so pe:-

"Ki l'ori ṣe t'ejika ko le ṣe? ejika r'ẹru o gba ọdunrun, ori ta tirẹ l'ogunlugba."

G. A. Oke

55, Hawley Street,
(Lafiaji) Lagos,
P. O Box 126
Phone, 27

July 1941.

# ỌRỌ AKIYESI

"Owe l' ẹṣin ọrọ bi ọrọ ba sọnu, owe li a fi nwa a" awọn baba wa a si tun ma npa lowe pe, "Bi owe, bi owe la 'lu ogidigbo, ọlọgbọn ni jo o, ọmọran a mọ ọ."